# ẸLETI ỌFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 912 LAGOS SATURDAY MARCH 14—MARCH 20 1964 KỌBỌ MEJI D)


**Dokita ORISU D'ALAGA:**

# Awon Agba Oselu Yoruba Binu Fi Ipade Sile Lana

EKO—Gbogbo awọn agbalagba oṣelu (Senators) Yoruba ti nwọn wa ninu ile igbimọ agba oṣelu ni nwọn binu fi ipade ti nwọn nṣe lọwọ silẹ ti nwọn tuka ni owurọ ana mọ awọn ti o wa ni ipade na lori ni Ọdan l'Eko nigbati nwọn nyan alaga tuntun dipo Oloye Dennis Osadebay ti o ti nṣe alaga apejọ awọn agba oṣelu na ri, ti o wa di Olotu Ijọba agbede meji Ipinlẹ Iwọ Orun ni Ibinni nisisiyi.

A gbọ wipe gbara ti nwọn ti da orukọ Dọkita Nwafor Orizu ara Nnewi ni ilu awọn Ibo kan wipe on ni awọn fẹ ki awọn yan ni alaga ile igbimọ awọn agba-oṣelu na ni Oloye Fagbenro-Beyioku, ọmọ ẹgbẹ Alakuko (NCNC) ti o jẹ ọkan ninu awọn agba oṣelu na ti dide ti gbogbo awọn Yoruba ti o wa nibẹ binu tẹle e; nwọn ni iwọsi ni ọrọ Dọkita Orisu ti awọn fẹ fi jẹ alaga na jẹ fun awọn nitori:e Yoruba ti alaga tọ si wa nilẹ nwọn ko fi ṣe e.

Fani-Kayode Sabe Niko

## Awon Yoruba Panupo Da Egbe Alajobi Sile

IBADAN— Ogunlọgọ awọn enia ni nwọn ti nki awọn aṣiwaju ẹgbẹ oṣelu ọmọ Yoruba ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ ti nwọn sọ ni ẹgbẹ Dẹmo Tuntun. A gbọ wipe orişirişi iwe ni awọn aşiqaju ẹgbẹ na ti ri gba lati ọdọ awọn Ọba ati ijoye Ipinlẹ Iwọ Orun.

A gbọ irohin ọkan ko ..ba atẹ luu nipa ẹgbẹ jọkan esi ọrọ ti Oloye Fani-Kayọde fi si awọn ti o tuntun na ni ana; o ni ilẹ ti awọn ọmọ Ibo jọ umu

(Wo yoku loju ewe kejọ)

Sangba Fo!

## Awon Omo Egbe Alakuko Pare Bi Ogan Ni Ibadan

IBADAN—Ọrọ agba bi ko ba ṣẹ lowurọ a ṣẹ lalẹ ni ti ọrọ awọn ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti nwọn fi bi ọdun mẹdogun joye opomulero ni igboro Ibadan ati agbegbe rẹ ti nwọn si ti sọ ara wọn di ẹyọ igbalẹ ti nwọn nyọ ninu ẹgbẹ na ni ọkọkan lati ijẹrin wa.

O ni irohin wa ni lati ọjọ keji ti nwọn ti da ẹgbẹ Dẹmọ tuntun silẹ ni awọn ọmọ ẹgbẹ na, awọn aṣoju ninu ile igbimọ aṣofin ni Ibadan ti nsare lati lọ forukọ silẹ ninu ẹgbẹ tuntun na, eyiti o ya mi lẹnu ni ti Oloye Fani-Kayọde, minisita alamojuto Ijọba ibilẹ gbogbo Ipinlẹ Iwọ Orun.

Oloye Fani-Kayọde kọ iwe si Dọkita Okpara ni Enugu wipe on kura ninu ẹgbẹ wọn, on ko fẹ ṣe ẹgbẹ na mọ. Lẹhin eyi ni awọn miran tun kọ iwe wipe awọn ko ṣe ọmọ ẹgbẹ Alakukọ na mọ.

### Adisa Fariga

Lẹhin ti Oloye Akintọla ti ba gbogbo awọn ara Ipinlẹ Iwọ orun sọrọ lori ẹrọ redio tan ni alẹ ijẹrin ni o ṣe ikede fun gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti nwọn jọ nṣe Ijọba pọ wipe ti nwọn ko ba tete wa forukọ silẹ ninu ẹgbẹ tuntun na, on a jọ wọn bi ẹni yọ jiga.

A gbọ wipe gbara ti ilẹ ti mọ ni ọkan ninu awọn Minisita alabaṣe pọ Ijọba Iwọ orun tiṣe ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) Ọgbẹni Adeoye Adisa ti fi iwe ranṣẹ si Olotu Ijọba, Oloye Akintọla wipe on ko ṣe iṣẹ minisita na mọ.

A tun gbọ wipe awọn alaga ibi iṣẹ ẹgbẹjọda mẹta pataki ni awọn ti tun binu fi iṣẹ silẹ ninu wọn ni ọmọ Eko kan ti nwọ npe Abiọla Oshodi ti ṣe alaga ile owo-nina wa, pẹlu Ọgbẹni Olajide Ẹsan ati J. A. Oyegoke.

(wo iyoku loju ewe kejọ)

Gongo So Ni Ibadan:

# Oloye Akintola So Oro Kobakungbe Fun Awon Egbe Alakuko

IBADAN — Ni oru ojo 'Ru ijeta Oloye Samuel Ladoke Akintọla, asiwaju Egbẹ Dẹmọ tuntun ti awọn ṣẹṣẹ da sịlẹ. Olotu Ijọba Ipinle Iwọ Orun ọkan - ko jokan ọrọ fun awọn asiwaju ẹgbẹ Alakuko ti t'on pẹlu ọn fi igbakan da ijọba ṣịṣe pọ ninu ọrọ redio.

## Egbe Alajobi

Ninu alaye ti Oloye Akintọla ṣe fun gbogbo awọn tị o ngbọ ohun rẹ o ni ko si idi tị awọn fi da ẹgbẹ tuntun yị sịlẹ 'ju ịwọsị atị ịrẹjẹ tị awọn ara on nị Ipịnlẹ Iwọ orun ti nfara da. O ni orịsịrịsị ọgbọn Ayịnịke tị po lị lọdọ awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC).

O sọ ịtan bị awọn ṣe bẹrẹ Ijọba 'a apọṣe l'Eko tị nwọn yan awọn ịkọ wa lati Oke Ọya o ị ịgbatị awọn ri wịpe ewu wa ninu kị Ipịnlẹ kan tobị ju ipịnlẹ kan lọ, nwon a forị kan orị awọn sị ṣe ịpịnnu wịpe kị awọn ge ịpinle ti o ba pọju sị wẹwẹ, awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ gba wipe awọn yịo fọwọ si, ṣugbọn ngb ti ọrọ na de ịle ose ni nwọn dehin kọ awọn ọmọ ẹgbẹ Action Group tị nwọn jọ ṣe ipinnu nigbana.

## Iwosi ati Ireje

Oloye Akintọla nisbati awọn nịọ se eto ilu in ilu Oyinbo awọn pẹlu Ẹgbẹ Alakukọ jọ pa imọ pọ wipe awọn ko nị fẹnu kan ọ o kị nwọn ja Eko kuru labẹ Ibadan. Gbara ti awọn ti de ijoko ajọ na ni awọn ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti bẹrẹsi sọ wipe da dan afi bi awọn ba yọ Eko kuro labẹ Eko.

Gbogbo awọn ti awọn jẹ ọmọ ẸGBẸ ỌLỌPẸ (AG) binu kuro nibi ipade na, awọn ṣebi awọn Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) a tẹle awọn ni, nwọn ko ṣe bẹ rara.

Oloye Akintọla ni kị awon to pada si ile ịpade na nwọn ti gbe nkan koja lehin awọn sibẹsịbẹ nwọn mu Eko kuro lara ịlẹ Yoruba patapata.

## Asiri Tu

Oloye Akintọla ni ẹgbẹ ALAJỌBI ni ẹgbẹ untun ti awọn ṣẹṣẹ da silẹ yi nitoripe awọn ẹgbẹ Alakukọ ti sọ awọn Youba di ọta awọn Hausa tan patapata, o ni kị ẹnu le ko ki awọn ma le di ero chin nibi Ijọba Apapọṣe tị awọn jọ ṣe pọ ni awọn ṣe da ẹgbẹ na silẹ.

O ni lọiọ tị awọn Hausa ni Oke Ọya sọ wipe awọn ko ti mura tan lati gba Ominira, awọn ọmọ ẹgbẹ ọlọpe ni nwọn ti si iwaju, tị awọn bi Ọba Ọni Ile Ifẹ, Oloye Enahoro on alara papa atị awọn bi Olọgbe Bode Thomas tị Oloye Arthur Prest ti awọn jẹ minịsita ninu Ijọba na binu fi iṣẹ silẹ.



ỌLỌLA BALEWA

Oloye Akintọla ni awọn ko mọ awọn ti nwọn ko awọn janduku kan jade wipe ki nwọn ma ho iho ole le gbogbo awọn oṣelu Hausa ti nwọn wa ni ile igbimọ asofin na. O ni gbogbo igbati awọn binu fi iṣẹ silẹ ko si ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti o binu tẹle awọn dipo eyi gbogbo adun ti o wa lọdọ Ijọba ni nwọn njẹ.

(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)



Olọgbe Oloye BODE THOMAS



Oloye SAMUEL LADOKE AKINTỌLA

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI-OFE

**Akoka Yoruba**

# Ayo Ominira Nigeria

## Lati Owo Alufa Atilade

Nipa eto titun yi, a da ile iṣofin mẹta silẹ : ọkan fun Ariwa, ọkan fun Ila Orun ati ọkan fun Iwọ orun ti Nigeria, a si wa da ile igbimọ iṣofin ti gbogbo ilẹ Nigeria silẹ ni Eko.

Ni akoko yi yi ni a da ẹgbẹ oṣelu ti a npe ni Action Group ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ati S.L. Akintọla ati N.P.C. ti Alhaji Ahmadu Bello, Saudauna Sokoto ati Alhaji Tafawa Balewa silẹ. Awọn Ẹgbẹ oṣelu wọnyi ee pataki pupọ ninu itan ilọsiwaju si ipo ominira ti Nigeria; nitoripe N P C lo di olori ẹgbẹ Aṣofin ti Ariwa; N C N C., ti Ila Orun ati Action Group, ti Iwọ Orun ti Nigeria ati pe nigbakugba, a ọn meji ninu ẹgbẹ oṣelu nlala wọnyi ni lati papọ ki nwọn to le ṣe olori ijọba ninu Igbimọ Aṣofin ti apapọ Nigeria ni olu ilu Eko.

Sibẹsibẹ awọn ẹgbẹ oṣelu wa ri i pe ofin Iṣelu ti Nigeria ti Ajẹlẹ Agba Richard ko dara to fun eto akoso ilẹ Nigeria; nitoripe ko fi aye fun gbogbo enia lati lọwọ ninu idibo lati yan awọn aṣoju n nu Ile Igbimọ Aṣofin. Eyi mu ki Ajẹlẹ Agba titun, Macpherson ṣe eto miran ti a nfi orukọ rẹ pe ni ọdun 1951. Biotilẹjẹpe, ofin titun yi fun ni ni anfani lati yan awọn igbimọ aṣofin lati inu ọpelọpọ awọn enia ti a darukọ fun yiyan, ati pe o si fun ni ni anfani lati yan awọn olori iṣẹ Ijọba ti a npe ni minister; sibẹsibẹ eto ti Ijọba yi ko tẹnilọrun. Eyi lo mu ki a ṣe eto ofin iṣelu titun miran ni ọdun 1954.

Ninu ofin titun yi ni a gbe fi anfani fun gbogbo enia ti nwọn dagba to lati dibo la i yan awọn ọmọ Ile Igbimọ ti Ijọba Apapọ ti Nigeria. Ninu ofin titu yi ni a gbe fi eto Ijọba Nigeria ominira le . Awọn Ipade meji nlanla miran ti awọn aṣoju Ẹgbẹ Oṣelu wa ni pẹlu olori Iṣẹ Ijọba ti awọn ilẹ okere, ti nwọn wa labẹ Ijọba Gẹsi jẹ lati ṣe ayẹwo awọn eto ofin titun ti ọdun 1954 ati lati fi ẹtọ ti ọmọ enia sinu eto iṣelu na. Eyi ni pe ọmọ enia ni ẹtọ lati ṣe isin ti o

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

# Ijoba Fowo Kun Aso Wiwo Ati Bata

EKO — Ọwọ olo o ni owo ma njọ si. Ijọba Apapọṣe ni inu ọdun ti a bọ si yi awọn fẹ fi owo kun owobode ọpọlọpọ nkan bi epọ mọto, apo si ẹnti aṣọ wiwọ, S mẹnti paapa.

Gẹgẹbi ìwe ikede ti Ijọba Apapọṣẹ fi sode nwọn ni apo pepa tab apo igbokun ti nwọn fi ndi okan wa si ilu a e owo si.

Ọṣẹ tab nkan ti nwọn fi nṣe ọṣẹ ti nwọn ba nmu wọ ilu ni lati le wọsi diẹdiẹ.

Akara Oyinb , ẹran inu agolo, panu abọmafọ pẹlu awọn nkan miran bi bata a awọ ti nwọn nko wọ ilu orişiriṣi lati ilu ajeji Awọn aṣọ ti nwọn fi siliki hun lati ilu okere wa ni Ijọba bu owo bode le lori ati rọba ẹsẹ mọto.

O o-bode ọṣẹ a i ẹr n tutu bi ẹ a d ẹ t a b i tolotolo ti ọn ti pa sinu yinyin ti nwọn ba ko wa si Nigeria fun tita ni a gbọ wipe Ij ba ni lati gba owo-bode lori wọn.

# Egbe Olomi Se Ipade Lori Enia Kika

Kaduna—Nkan ti aboyọri enia kika ti wọn kan wa ... ọdun ti o kọja yio da silẹ ko ... nitoripe lati ọjọ ti nwọn ti ṣe ikede iye ti nw fi wa ka na ni wahala ti de be si gbogbo awọn ... u Ijọba wa ọ un losi.

N Kaduna ni a tu bo ... ipe awọn ọmọ ẹgbẹ ... mi (NPC) pe ara ... ni ijerin ti n w ọ n si ṣ e ipade n l a kan Ipade ... dun wọn lọ ... tobẹgẹ ti o fi jẹ wipe ... ṣe ni nwọn ti ilẹkun mọri Ẹ ... ọrẹ w ọ n a sọ fun wa wipe ibayọri enia kika l nwọ i ... un mọ riṣọ. A tu g wipe gbo— gbo ... ati awọn ijoye ... a paap tun ṣe ipade ti w ọ n lọ tọ. Nwọn ... wọ faramọ bi nwọn ti ka awọn enia na si.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

## African Film Technicians Take Course In London



Holding a large model of a light meter, the Principal of the Overseas Film and Television Centre in London question students about different models they are holding. Next to the wall is Mr. J B Shanu-Wilson, from Freetown Sierra Leone, with Mr. L A Mwamlima, f om Karouga, Nnasaland, next to him. Second from the right is Mr. T A Awogbayika, from Owo, Nigeria.

The Principal, Mr. Spurr is responsible for a year long course in which the students-including 12 Africans-learn the basic techniques of film making before specialising in tee activities that interest them most, such as film editing, scfipt writing or camera operating.

ELETI-OFE
(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosoko Street, Lagos; P. O. Box 467
CABLE & TELEGRAMS "ELETI-ỌFẸ" LAGOS Phone 29870

VOL. XLV. NO 912 SATURDAY March 14—March 20 1964.

## Oro Olotu:

# Agbalagba Ki Wa Loja ...

Awọn Yoruba ni agbalagba ki wa lọja ki ori ọmọ tuntun pa, ọrọ alufasa kan ti Alhaji Ahman Galadiman Pategi Minis ta alamojuto isẹ ọgbin ni oke ọ y a sọ s Ọlọla Nnamdi Ayikiwe, alakoso Ijọba Apapọ lara ninu ile Igbimọ wọn ni Kaduna lọse ti o kọja ni a fi fẹnu kan iwa agba ti Ọlọla Ahmadu Bello, alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa hu nipa ọrọ na.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ nipa ọrọ afojudi ti Alhaji Pateg sọ na, nwọn ni o ni Ọlọla Azikiwe padanu aye ijoko rẹ ninu ile Igbimọ Asofin Ipinlẹ Ila Orun nibiti o gbe nja ijakadi kakiri lati bọsi ipo Alakoso Nigeria.

## Ki Ori Omotuntun Pa

Wara were ti Ọlọla Azikiwe ti gbọ ọrọ yi ni o si fesi wipe irọ nla ni Alhaji yi n p a ati p e ki o maṣe fi didakẹ on pe on ni omugọ. Ọlọla Azikiwe ni on fun on ni on fi ipo ijoko on silẹ ni Enugu lẹhinti nwọn ti tun dibo fun on lati wọle Igbimọ Apapọse l'Eko.

Ọrọ na mu ki inu bi Ọlọla Azikiwe o si sọrọ ti ko ba ilu mu fun awọn ti o moye pọlu ikilọ wipe ijangbọn ni nwọn fẹ da silẹ ni Nigeria bi nwọn ba n sọ iru ọrọ bayi si ẹn ti nwọn npe ni olori Ijọba wọn.

Gbara ti Alhaji Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto tise olori ẹgbẹ Olomi (NPC) ti gbọ w i p e ọrọ na bi Ọlọla Azikiwe ninu ni o ti tẹ waya ẹbẹ w i p e awọn tuba si i wipe ki o maṣe fi ọrọ na ṣe ibinu rara.

Tani le sọ wipe inu iwa ti Sardauna yi hu ko dara ? Bi a b a ti m ọ ẹjọ n i ẹbi a ki p e ni ikunlẹ, sugbọn ki Alhaji Pategi maṣe jẹki a gbọ iru rẹ mọ laiilai.

# Egbe Demo Tuntun

Igba ara ni a nbura, awọ agbalagba ni a ki bu Sango ninu ẹrun; awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ba gbo gbo awọn asiwaju ẹgbẹ oṣelu ti nwọn ko ara wọn jọ ni Ibadan ni ijẹrin lati da ẹgbẹ oṣelu tuntun kan silẹ ti nwọn sọ orukọ rẹ ni Nigerian National Democratic Party-Ẹgbẹ Dẹmọ ti Nigeria.

A gbọ wipe ko si nkankan ti o jẹki awọn oṣelu yi da ẹgbẹ tuntun yi silẹ ju iy pa ti o wa larin awọn oṣelu Ipinlẹ Iwọ Orun lọ, ṣugbọn awọn ọmọ ẹgbẹ tuntun yi fẹ na asia irẹpọ sode ki nwọn le pa ina awọn ti o ma nfi igba gbogbo wa larin orişirişi ẹgbẹ oṣelu ti nwọn wa ni ile igbimọ aṣofin:

Bi oju ko ba ti ole, oju nti oni nkan. Bi oju ko ba ti awọn oṣelu wa ti a ran lọ si ile Igbimọ wipe ki nwọn lọ ṣe aṣoju fun wa nibẹ, ti o jẹ wipe ojojumọ ni wọn nja, ti nwọn nhu iwa ọtẹ si ara wọn oju nti awa aborikuru ti a ran wọn lọ si ile Igbimọ aṣofin na.

Nwọn ni a ki gbọ ariwo ninu ile agbalagba ni emeji; bi o ba ti jẹ wipe nitori ki irẹpọ le wa larin ilu, ki a le ko ere oko dele ni a ṣe da ẹgbẹ yi silẹ, adura awa Eleti-Ọfẹ ni wipe ki Olodumare le ba wọn lọwo si ero wọn nitoripe ATẸWỌ ẸNI KI I TANNIJẸ.

Ọrọ re o, ẹnyin ọkawe wa Ẹgbẹ Dẹmọ tuntun de.

# Iwe Si Olotu

# E Ku Ewu !



## Obabinrin Elizabeth Keji

Ni oru ọjọ Isẹguu ni a gbọ irohin wipe Ọlọla Ọbabinrin ilu Oyinbo, Elizabeth Keji bi ọmọkunrin jantojanto kan ni London fun ọkọ rẹ Ọlọla Philip. Eleyi ni o di ọmọ kẹrin ti Ọbabinrin na yio bi lati igbati o ti jọba gbogbo awọn ọlọla ọlọla ati awọn Ọba agbaiye ni nwọn si ti nki i ku ewu ti ọmọ na.

ỌRỌ OLOTU:

# Nihin Lohun Ati Ni bi Gbogbo

## Demo Lo L'Eko

Ẹnyin ọkawe mi o dun mi pupọ ti nko s ni Ibadan ni owurọ ijẹrin ti nwọn da ẹgbẹ tuntun kan s iẹ ni ile Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, Oloye Sam Ladoke Akintọla ni Iyaganku lọna Abẹokuta. Mo gbọ wipe Ẹgbẹ Dẹmọ ni nwọn fẹ lati ma pe ẹgbẹ tuntun.

Ẹnyin ọkawe mi ti ẹ ba ti mba awọn oṣedu Eko rin l ti nkan bi ogoji ọdun sẹhin a mọ nkan ti Olo-gbe Herbert Macaulay fi Ẹgbẹ Dẹmọ ṣe nilu Eko, mo si ro wipe nigbati ẹgbẹ Dẹmọ ti wọkọ pajawiri lọ si ilu Ibadan, a le f'oke Mapo ba lọ si Oke Elerin ni Ogbomọshọ ati Oke Kiri ni Igbajọ.

## Egbe Aladapo De !

Mo gbọ wipe Oke pọ ni agbegbe Ọshun bi Oshogbo, Ọtan Aiyegbaju, Ẹdẹ ati Ejigbo ati pe Oloye Kọla Balogun paapa ti npalẹ ogun mọ lati ko ẹgbẹ.

## Lati Owo Ayiluka

Ọlọpẹ damọ Akukọ lọ si ebute tuntun gbogbo ọrọ na wa toju su emi Ayiluka, boya inu awo awọn ọmọ ẹgbẹ tuntun na ti nko si ni onda ẹru ba mi sugbọn emi Ayiluka a ri iran wo ninu eyiti a tun bọ si yi nitoripe gbogbo aiye ti di ẸGBẸ ALADAPỌ ni Ipinlẹ Iwọ orun.

Oloye Fani-Kayọde, alagbara paapa ti bi awọn Ẹgbẹ Dẹmọ Aladapọ lọ, lọni ọrẹ mi Seriki Tulasi Adeleke Adedoyin. Awọn ni nwọn da orin Dẹmọ lo l'Eko silẹ nigba ọtẹ Area Council. Mo ro wipe orin na a d Dẹmọ lo ni Oke 'Badan t o fi de Ogbomọshọ; ẹ jẹki a mọ wo o.

## E ku Ewu

Emi Ayiluka ba ọkọ obabinrin ilu Oyinbo yọ fun ọmọkunrin kan ti iyawo rẹ ọba Elizabeth bi ni ọjọ Isẹgun. Ọluwa ki o da ọmọ na si sugbọn bi a i bi ẹru ni a bi ọmọ.

# Ina Jo Abule Kan Ni Jos

JOS — Ina kan ti o jo ni osa gangan mu awọn e'e h ti nwọn wa abule an ti nwọn npe ni Gana Raji jade si gbangba ni ijẹta. Ofo ti ina na ṣe awọn ara abule na ko kere rara.

Onirohin wa ni bi ti a na se bẹrẹ ko ye ẹ ikan rara ninu awọn ara abule na ; abule na ko ju ọgbọn mal lọ si Jos, o ju igba ahere lọ ti ina na jo kanlẹ.

Baba Hausa agbẹ kan ti o ma agbẹ ọdunkun ti awọn Hausa npe ni Dakali ni gbogbo owo pepa ti on ko pamọ sile ni ina na jo atapata ẹu awọn aṣọ on. A gbọ wipe baba na ko si nile, o ti lọ si oko rẹ nigbati na bẹrẹ.

Gbogbo awọn enia ti ina na ṣe lese ni nwọn ti ko wa si ile alaisan ni Jos.




# Eleti-Ofe Daraba

# Owo Awon Olopa Te Baba Gbomogbomo

Onitsha—Ọwọ awọn ọlọpa Onitsha ti tẹ baba-gbọmọ gbọmọ kan ti o fi ọgbọn ko awọn ọmọ ọlẹmọ lọ si ilu rẹ ni ọna Awka lati ta wọn. Awọn ọmọ kekere mẹta ni gbọmọgbọmọ na jigbe nibi ti nwọn gbe nṣere wọn lọwọ.

A gbọ wipe ni ọjọ ti okunrin gbọmọgbọmọ yi gbe awọn ọmọ na ọmọ kan ti nwọn npe ni Patricia Ezendu ti awọn jọ nṣere pọ ni o kigbe ti gbogbo awọn ara adugbọ fi jade ti nwọn si le ọgbẹni gbọmọgbọmọ na ba.

Awọ Ọlọpa ni akara ni o fi tan awọn ọmọ na ki o to ma ko wọn lọ; nwọn ni oisegun ni baba-gbọmọgbọmọ na; o si ti ko awọn ọmọ mẹtẹts na de idi ọkọ Asaba ki ọwọ to tẹ ẹ.

Nwọn ni orisirisi egbogi afọṣẹ ati igbadi ni awọn ba lọwọ gbọmọgbọmọ na lọjọ ti awọn ọlọpa muu.

---

# Egbe Olomi Se Ipade

(O bere loju ewe keta)

Nwọn ni awọn ngbẹ ti Dokita Okpara nṣọ kiri wipe Ijọba on ko faramọ ibayori enia kiba na ati wipe on fẹ ki gbogbo awọn olotu Ipinle kọkan wa si Eko lati ṣe ipade lori ọrọ na Nwọn ni awọn ko fẹ ki Oletu ti Ipinle awọn ki o lo si ibi ipade na rara

A gbọ wipe Dokita Okpara paapa ti fanke kọri wipe on ko ni yi ọrọ on pada lori magomago ti nwọn ṣe lori enia kika na.

---


E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin

ELETI-OFE

ti o kun fun irohin aladun losose.


# Ayo Ominira

(O bere loju ewe keta)

ba wu u, lati ṣe iṣẹ ti o ba wu, lati ko ọrọ jọ ati lati gbadun ilo rẹ. Ofin t tun yi lo gbe ilẹ wa de ipo ominira ti a gba ni ọdun 1960.

Fun ajọyọ ti ominira yi, a pe gbogbo awọn Ijọba pataki, pataki pe ki nwọn wa ba wa yọ ayọ ominira na ni ọjọ kini oṣu October ni ọdun, 1960. Ni idahun s ipe yi, awọn aṣoju ijọba wa latiU.S.A., Canada, India, Japan, China, Syria, Egypt, Etoopia, Guinea, Wes ern Germany, Sweeden, Denmark, United Kingdom, Ireland ati lati awọn ilẹ miran. Awọn oniwe irohin ju adọjọ lọ ti nwọn ti oniruru ilẹ ajoji wa. A pe awọn ajẹlẹ, awọn ojiṣẹ Ọlọrun ati awọn olukọ ti nwọn ti ṣiṣẹ ni Nigeria lati wa ba wa yọ ayọ ominira. Eniti o wa lati ṣe aṣoju Ọbabinrin Elizabeth II ti ilẹ Gẹsi ni ọmọ ọba Alexandra ti Kent a si ṣe ilu Eko ti iṣe olu ilu Nigeria lọṣọ fun akoko ajọyọ na.

Nigbati ọjọ ominira ti ku bi ọsẹ kan ni ọmọba Alexanra ti de, o si ni anfani lati woran awọn ere ti o ṣalu eto ti ọjọ ominira bi eto iwọ kọja ti awọn ọmọ ile ẹkọ ati awọn ọmọ ile ẹkọ ati awọn oriṣiriṣi ori ilẹ ere Race Course. A nlo woran awọn oniruru iṣẹ ọna iṣẹ ọwọ ati awọn nkan ti a nri lati lati inu ilẹ inu oke inu igbo ati orisirisi nkan ti a nfi ẹro ṣe ni Nigeria ti a ṣe ifihan ninu awọn ile nlanla ifihan ti a kọ si Erekusu Victoria ni ọna Oku ti Eko.

Ni alẹ aisun ti ọjọ ominira Friday September 30 1960 gbogbo awọ alejo ti a fi iwe pe ati awọn onile ti a fi iwe pe ati awọn onile ti a fi iwe pe peje si orile Race Course ni Eko ni ago mokonla alẹ. Lẹhin igbati awọn ọmọ ti ṣe ere ogun jija tan, ni ọmọ ọba Alexandra fi iwe aṣẹ ti ominira Ilẹ Nigeria le le Aṣoju Ijọba Apapọ Ilẹ Nigeria, Alhaji Tafawa Balewa lọwọ awọn ologun kọ orin ("K' Ọlọrun d' ọba si") ibile ti Ijọba Gẹsi, lẹhin eyi a pa ina electric bi a ti nfa asia Ijọba titun ti Nigeria soke. Bi a ti tan ina pada, titun ti Nigeria soke. Bi a ti tan ina pada asia ilẹ Nigeria ni a ri l'oke, awọn ọmọ ogun si kọ orin Ibilẹ ti Ijọbo Nigeria ('Nigerigeria, a ki ẹ, Ibilẹ wa ọwọn").

Ni ago mẹjọ arọ ti ọjọ Saturday ti iṣe October 1,1960, gbogbo enia ti a fi iwe pe onile ati alejo tun peje si ori Ilẹ Race Course kanna nibẹ ni Ọmọ Ọba Elexandra gbe fi iwe ofin titun ti ilẹ Nigeria Ominira fun Asiwaju Ijọba (Prime Minister) Alhaji Tafawa Balewa Olori Adajọ Agba Adajọ Adetokunbọ Ademọla si ṣe ibura fun Sir James Robertson bi Ajẹlẹ Agba kini ti apapọ Nigeria Omira

Fun edidi ọsẹ kan gbako lẹhin ọjọ ominira yi, ijo ayọ jijẹ mimu ati sisa ere ije l' ori ilẹ are titun ni Surulere ni a si nṣe ajọyọ ti ominira. Ki ọmọba Alexandra to le pada lọ si ilu Oyinbo, o to ọsẹ meji lẹhin ọjọ ajọyọ ominira: nitoripe o lọ si Ibadan ti iṣe olu ilu ti Ijọba Iwọ-Orun ti Nigeria. Ki o to kuro ni Ila Orun, o lọ si Nsuka lati si ile ẹkọ nla ti "University Nigeria" Nigeria Nigbati o kuro ni Ila Orun ni o lọ si Kaduna ti iṣe Olu Ilu ti Agbegbe Ariwa ti Nigeria. Nigbati o kuro ni Kaduna, o lọ si Kano lati ibiti o gbe ti wọ ọkọ ofurufu pada lọ si ilu Gẹsi lati lọ jihin abọ fun Ọbabinrin, Elizabeth II, eniti o ran a niṣẹ.

Fun ajọyọ ti Ominira yi, gbogbo awọn ilu ati Ilẹ ominira ni awọn ki ilẹ Nigeria Ku ori "rei" nitoripe Ominira wọle wa laisi ija ati itẹjẹsilẹ. Ki Oluwa jẹki Ominira na jẹ onjẹ ajẹpẹ fun wa ati fun awọn ọmọ, ọmọ wa lailai Amin.

## Your Radio Next Week

# Education: A New Approach

## Professor's Views in BBC Broadcast

The educational systems of new African countries are in a good position now to absorb new ideas and to make changes. An eloquent appeal for educational changes that are relevant to Africa is made by C.H. Dobinson, Professor of Education at Reading University, in his new book 'Education 1916-1970.' He spoke about his ideas in the BBC African Service programme FOR PARENTS AND TEACHERS which can be heard every Saturday at 11.15 GMT on 21.81 and 21.615 megacycles in the 16 and 13 metre bands.

Asked what changes should be made in the educational systems of African countries to ensure the best possible education for children, Professor Dobinson replied: 'First, there must be more education. Second, I am convinced that there should be far more opportunity for personal observation experiments and activity by the pupil. The emphasis given to learning material and the purely literary arts should be reduced. That, in my opinion, is overdone in Africa today. Children should be encouraged to look at their environment, to study and observe the things around them. They could then form opinions as a result of confidence in their own powers of observation,

## More Practical Studies

While in West Africa Professor Dobinson had noticed the importance with which Latin was regarded. He considered that scientific observational studies would be of far greater importance, biological studies in particular. .I believe youngsters would find a wide range of scientific and practical studies far more to their taste. They should be given far more opportunity to use their hands. For almost every boy and girl delights in acquiring a skill of some form with his hands."

## Too Many Exams

Speaking of examinations, Professor Dobinson said: 'We have got to free ourselves from the conception of applying the same examination paper to thousands of young people. This attempt to establish uniformity of standards is, I think, a mirage." They were not really uniform, but in the course of doing this young people were driven to learning the same things, and then to regurgitate them.

Written examinations should be replaced by tests that would show what a person could do and was caphie of in the future. These tests should be largely practical and not timed against the clock. "We must somehow or other try to free ourselves from this obsession with a piece of paper that is gained by taking an examination largely based on memory."

## Chalk And Talk

Professor Dobinson said that what was wanted in primary schools was small classes so that the teacher could minister to the needs of individuals. This could be done, because if money were spent on teachers for small groups in primary schools this could be compensated by allowing large groups of 100 or more in secondary schools to see documentary film or television lessons. After they had seen them, the pupils could then work on their own, and this would also economise teaching power.

"At present," said Professor Dobinson, "most of our school days are filled up with chalk and talk, lesson following lesson with very little opportunity to digest and mull over what has been heard or seen. I believe that the pupils could profit very much from having at least one half day for private study on school premises."

He also advocated a larger scale use of secondary schools, provided some of the time was spent in laboratories or workshops. Teachers could be present to see that all went well, but need not be actually teaching. The pupils could be working with their own particular projects, just as he had seen in the evening activities of Swedish schools. "Every school that has equipment should use its equipment for as many hours of the day as possible. It is bad, at present, we close the schools about four o'clock and the equipment lies idle. I am sure that African countries, which must make the most use of all the things they have, can set an example in this way."

## BBC NEXT WEEK

During the coming week programmes in the BBC African Service after the News at 12 o'clock (local time on 17 81 and 21.615 megacycles in the 16 and 13 metre bands will be as follows:

| | |
|---|---|
| Sunday, March 15 | London Fanfare |
| Monday, March 16 | A Book For Today, Forcus On Africa Around The Town With Sherman Brown For You At Home. |
| Tuesday, March 17 | A Book For Today Postmark Africa African Mirror Calling Ghana |
| Wednesday March 18 | A Bo F T d F cus O Af c f c The t e |
| Thursday, March 19 | A B F T d F cus O c D c C ing ge |
| Friday March 20 | F T F D W |
| Saturday March 21 | Sho jm Teaches. C Leone |

Daily at 11 00 GMT World N[illegible]
Daily at 11. 30 GMT News Of [illegible]

Read And Advertise In Eleti-Ofe
Your Weekly Newspaper.

### Gongo So Ni Ibadan:

# Oloye Akintola So Kobakungbe Oro Fun Awon Egbe Alakuko

(O bere loju ewe keji)

Oloye Akintola ni ki enu awon omo Yoruba le kon ni awon se da egbe tuntun na sile, o ni n Oke Oya enu awon omo egbe Olomi (N P C ) to le, nwon se nje s ow won; ni ilu awon Ibo, enu egbe awon Alakuko (N C N C ) to le sugbon ni odo wa nibi ni gbogbo nkan ti yato.

## Amugbalowo

Oloye Akintola ni lodo wa ni wa ti ri egbe oselu orisirisi O ni o ba de odo wa wa ba egbe A.G., NCNC, UPP, PWD., GBO, UAC., CWS ati orisirisi awon egbe ti ko ni oriki.

O tun toka si i ninu oro re wipe eyiti awon omo Yoruba se amugbalowo to. O ni bi a ba de ibi se patakipataki awon ti nwon ni ki a ma ba awon ara Oke Oya da nkan po mo rara Ibi wa ma ba ni ori aga, awon omo Yoruba wa tun di eniti ko mo nkan se mo. Oloye Akintola ni eyiti awa Yoruba se amugbalehin to.

## Aja Ode

O ni awon omo egbe Alakuko so awon omo Yoruba di aja ti o npa eran fun won. O ni gbogbo wa ni a ma Aja ode ti nwon npe ni TANI TOLORUN. Bi awon ode ba mu u lo sinu igbo ti won, ba foju kan eran nwon a de e si i, ti o ba si ti ki eran na mole, oju awon ode a yan, nwon a ma wa logun wipe, e ba eran yi lenu TANTO ORUN, e m je ki o je.

Oloye Akintola ni gbogbo wahala ise ti omo Yoruba se ninu ise oselu awon omo



Oloye OLU AKINFOSILE

Iho ni nwon nje anfani ibe. O ni gbogbo eniti o ba nfe ilosiwaju awon omo Yoruba ni lati wo egbe Demo tuntun yi.



Olola NNAMDI AZIKIWE

## Awon Omo Egbe Alakuko

(O bere ni oju ewe kinni)

Awon oga pataki ni ibi ise Ijoba ti nwon je omo egbe Alakuko ti nwon tun binu fi ise won sile ni a ka meji kan, awon Ogbeni Y. B Abioro ati O. A Obadara.

## Egbe Alajobi

(o bere loju ewe kinni)

nidi Ignadu ni o jeki nwon se ara won lokan, o ni bi ko na ba si tele awon on lehin ko si wahala nibe, a fi awon ti ko ba mo nkan ti o nlo ni nwon le da on lebi Nisiiyi NNDP ti di 59, AG. 27, NCNC merin pere lo wa ni ile Igbimo ti Ibadan.

THE ANSWER TO TROPICAL CONDITIONS

★

UNMATCHED AFTER SALES SERVICE

★

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street Lagos Phone 23370 Editor; (Oloye) Ola Onatade, 15, Kosoko Street, Lagos, P O Box 467.